# ALUFA APALARA KEJI TUN DE O!


AWOGBA Omode fun Girl, Eyi, Hihu-ehin, Ower. Ra Tir Ni Ile Ezbogi — ISE — Oludamare Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St., LAGOS

ELETI OFẸ
A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJO

TO CLEAR
Gents Suede Court Shoe
Brown, Black & Grey
Before 50/- Now 42/6
Obtainable at :-
A. B. AKINYẸMI
10A Moloney Bridge St
LAGOS.

VOL. No. VIII 473. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, JUNE 23, 1956. KỌBỌ MEJI (2d.)

## Alufa Apalara Keji Tun De O!

ASINFO. A gbọ irohin lati ilu awọn Aganyin wipe ọkunrin kan nṣe wasu kiri ilẹ na, o pe ara rẹ ni Apalara, o si nṣe wasi kiri, o we lawani rebete o nsin awọn Oloro jẹ, o nsin awọn elegungun jẹ o si ni ọlẹ oloju meji kan ti o ma nmu dani rin.

Nigba gbogbo l o ma nleri wipe ko si eniti o le fi on ṣe kinikan, awọn enia a si ma pọ ninu wasi rẹ.

Lọjọ kan ti nwọn fẹ ṣe odun Egungun nilu Asinfo, a gbọ wipe ọkunrin ti o pe ara rẹ ni Apalara yi lọ tẹtafo wasi sibiti nwọn o ti ṣere Egungun na.

Alufa na nṣe wasi l'ẹgbẹ kan, awọn Egungun njo l'ẹgbẹ kan, Egungun kekere kan sare wọ inu agbo ọdọ Apalara, ni alufa ba tu u si ihoriho. Eyi mu ki inu bi awọn elegungun, nwọn fa ada yọ, nwọn si mbọ wa ba alufa, ni Alufa Apalara ba ṣiyan ti ko duro gba ọbẹ, o si salọ bamubam.

ỌRỌ ỌLỌRUN KO MU IJA WA

Awọn alufa ti ma nsọ lojọ pipẹ wipe ọrọ Olọrun ko mu ija wa. Ẹniti nwọn ba sọ fun, bi ko ba gba, ki a fi silẹ nitoripe keregbe ti ko loju, a ko le fi tulasi fi mu'mi. Pẹlu-pẹlu olin Gẹsi ti a nlo nisisiyi, ko gba ki a fi agbara mu enia lati ṣe esin ti ko ba fe. Alufa Apalara ti Oko Baba ti ṣe tirẹ, o si yanju kedere, ṣugbọn ẹnyin adamọdi Apalara ẹṣọ di ọwọ nyin o.

THE NATIONAL BANK

**Of Nigeria Limited.**

Ile ifi Owo pamọsi yi
Nfi ọna owo han eni
Bi o ba fẹ jẹ onisowo pataki ao
ran ọ lọwọ nipa wipe ao tọ ọ
si Ọna ti o dara, ao la oju rẹ
si Ọna owo lati ilu Okere wa
Bakanna si ni a tun nṣe iranlọwọ fun
gbogbo oja ilẹ wa ti anta si agbaiye.

ILE IṢẸ WA NI EKO :—
37, Marine Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.
The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.

## Oluwa Sise Re

ORIỌLA R'ORUN



Awọn Yoruba mọnimọni, bi nwọn ba daro enia titi ni ẹhin iku rẹ, nwọn a wipe "Oluwa ko iṣe rẹ de"! gbolohun yi nikan ni a le fi tu ọfọ iku ologbe Shafi Olatunji Oriọla, ọdọmọkunrin bọlọjọ ti o fi aiye silẹ ni ọjọ Wednesday ti iṣe ogunjọ oṣu June, ti a si rẹ oku rẹ tẹ sinu Iboji ni ọjọ kọkanlelogun oṣu June, 1956.

IṢẸ WỌN NTỌ WỌN LẸHIN

Ni igbesi aiye ologbe yi, enia rere ni iṣe, O ṣiṣẹ aje ni owuro ọjọ rẹ, o si na owo rẹ si ọpọlọpọ ibi anfani, ọkan pataki ninu alatilẹhin ẹgbẹ Ansarudeen Soceity, o si na owo ribiribi fun awọn oṣere Football l'Eko. O ṣe iṣẹ ribiribi silẹ, ṣugbọn ko duro lati jẹ ere iṣẹ rẹ na.

Ha! iku doro, iku ṣ'ika, iku iba gb'owo, iku iba gb'ẹran, koba dara julọ. Oriọla ku lait'ọjọ.

Otitọ ni ọrọ Ọlọrun to sọ bayi wipe "Ina lilah, wa ina ilehin rajiuna." Ọdọ Ọlọrun ni a ti wa, ọdọ rẹ ni ao si tun pada si: awọn enia wa Yoruba, akewu-mani-akọsilẹ ni nwọn ma sọ wipe iku pa Babalawo bi ẹniti ko gbọ'fa, iku pa Onisegun bi ẹniti ko ni ogun, iku pa Alufa bi ẹniti ko nke si Ọlọrun. Iku pa Oriọla, ẹni're r'ọrun.

Ki Oluwa fisi ibusun rere.

## Ipade Awon Onile ti nwon fe wo'le won.

EKO. Nigbati awọn ara Eko pejọ lọjọ Monday ọjọ 18th oşu June si ita gbangba ojude Dokita Maja lati gbọ ohun ti akọnẹ wọn Alhaji Maşa ba rọ lati ọdọ awọn oyinbo ti o nfẹ wo gbogbo ilu Eko lulẹ, ti nwọn si fẹ le awọn Onile, Onilẹ lọ si Surulere lẹhin odi.

Awọn ero pọ bi omi, nwọn ko si tete bẹrẹ ipade na nitori pe awọn nduro de Ọgbẹni T. O. S. Benson ati L. J. Dosumu asiko si ti lọ jọjọ ki nwọn to bẹrẹ.

Nigbogbo igba ti Alhadji Maşa nka iwe ti awọn oyinbo ti o fe w'ole ko fun awon enia, nşe ni gbogbo enia nkigbe, ti nwọn si npariwo wipe, a ko ni ... a ko gba! gbogbo ... ṣọ oyinbo ... awọn eni ko ... wipe, a ko ... a ko ni fi ile wa ati ilẹ wa silẹ lọ sibom ...

Bi Alhadji Maşa ti pari ọrọ rẹ tan ni Ọgbẹni Benson ba bẹrẹ si şe alaye, o wipe, on nikanşoşo lo jẹ igbimọ Alakuko ninu igbimọ na, şugbọn ẹnikan ko fi iwe jişẹ fun wọn wipe awon ara Eko ko fẹ eto ile wiwo na.

Şugbọn ẹnikẹni ti on gbọ ti awọn enia sọ wipe nwọn ko gba yi, on yio mura lati gbe ọrọ na siwaju pe awọn enia na ko gba ki a wo ile wọn, gbogbo eto bi nwọn ti nşe igbimọ wo'le-wo'le na si ni on yio fi le Alhadji Maşa lọwọ.

Nwọn so wipe gẹgẹbi nwọn ti ko opopo ọna Jankara si Ehin ogba bẹni nwọn fe kọ Esiti nwọn na si ya ni ọkọ fi kọ'le, ti o ba ya Ọgọrun pọun yio san ẹgọ dipo. Pẹlu idarudapọ ni ajọ na fi tuka nitori awọn enia ko ni inu didun si imọran L. E. D. B.

## NIBO NI YORUBA TI ŞE WA ?

IBADAN. Ijọba ilẹ Yoruba ti yan awọn ojọgbọn ti ori wọn ti pe lati mọ ilu wọn ni iran Yoruba gbe ti şe wa ki nwọn to wa tẹdo silẹ Ife.

Nitori ero yi, Ọkẹ meji poun (£40,000) ni ijọba fẹ̀ ọrun fi lelẹ fun awọn ojọgbọn enia ti a o ran lọ şe iwadi na.

Dokita S. O. Biobaku ni yio ko awọn enia na sodi lọ silẹ Khartoum lati şe iwadi na.

Ọlọla Awolọwọ sọ ni j si nigbati o nlọ silẹ India ti o de ilẹ Sudan, o şakiyesi pegebi awọn ara ilẹ na ti fi oju ati ara ati işesi wọn jọ Yoruba nitori pe Ọ ipele wa ninu wọn, Alaraja wa, Onikẹkẹ, Onirọmbọ, ati Onibaramu Iye awọn enia ti a yan ti yio lọşe iwadi na ni, Oloye I. O. Delano, Ọgbọgi ninu ede Yoruba, Ọgbẹni S. A. Ogunkọya Arọkin Fẹla Şowande, Akọrin ilẹ Yoruba, Ọgbẹni Akeredolu, Agbẹgi-lere Yoruba, Ọgbẹni Ulli Beir, Iran Yoruba ilu Dahọmi, Ọgbẹni Pierre Verger, Iran Yoruba to şi wa ni Oko Ireke ni Brazil Oloye J. Igharevba ti o je iran Yoruba ati Ibini papọ.

Ki nwọn to de Khartoum, nwọn o duro şe iwadi diẹ nilu Sudan.

## Ara Ibadan fe ko Mosalasi Jimo titun.

IBADAN. Gbogbo awọn ijọ Musulumi ilu Ibadan lo pejọ lori enivan wipe, nwọn nfẹ kọ Mọşalaşi Jimọ titun eyiti yio ba ode asiko yi mu ati pe yio na wọn ni owo ti o pọ to ọkẹ meji abọ poun. (£50,000) Alhaji Muili ti o nşe Imam Jamiyu ilu Ibadan gba awọn Jọmma niyanju wipe gbogbo awọn Lemọmu Ratibi ti o mbẹ ni Mọşalaşi kọkan ti şe ileri wipe pẹlu Ogo ati atilẹhin Olodumare, iyekuşe ti nwọn ba bu fun Jọema Mọşalaşi wọn, wọn yio da a jọ.

Ki ẹnikẹni ti nwọn ba bu owo fun maşe jafara lati san tirẹ. Diẹ ninu awọn Imale ti o tun sọrọ na, Oloye Salawu Aminu, on lo si kọkọ fi owo tirẹ lelẹ, o da pọun mejile-ladọta ati şile mewa. Iyalode Ibadan ati Alahaji Şoye, Balogun ilu Ijẹbu Ode şe ileri wipe on yio gbe ọdidi mọto Ako-ero kan silẹ wipe on fi ta Jọnma lorẹ, owo ti mọto na ba npa ki nwọn ma le fun kikọ Mọşalaşi na. Alhaji Şoye yio fi mọto na ta Mọşalaşi l'ọrẹ patapata ni o.

## Ogun Ijebu Ode

Ni ọdun 1892 ni irohin kan titi de ilu Eko wipe awọn Ijẹbu ti s'ena ti nwọn gba koja lọ si Ibadan, nitoripe, eniti o ba ngbe ilu Eko ti o si fe rin irin ajo lọ si Ibadan ọna Ijẹbu Ode ni nwọn ngba.

Nigbati ọrọ ri bayi, Gomina Eko ran Iko si Ọba Ijẹbu-Ode wipe ki o jẹki awọn enia raye koja, irohin tun de wipe Awujalẹ da awọn Iko na jeko. Inu bi Goloba, o ko awọn Ọlọpa sinu ọkọ, nigbati awọn gunlẹ si Ejinrin, nwọn ko ri eyo Ijẹbu kan.

Awọn Ọlọpa ko mọ ibiti, nwọn ma gba, awọn ara Ibadan lo pọju ninu Ọlọpa lasiko na, nşe ni ara nya wọn lati jagun na nitori awọn ni ibọn Poopoo atidiki jọwọ ti o le rin to iwọn busọ meji.

Abudu Saji jẹ ọkan ninu ọga Ọlọpa nigbani, o'nfẹ şe ofin toto gbogbo oja Ejirin yika lati ri pe ko si awu lẹhin ki nwọn to tẹsiwaju.

O gun ẹşin, o si mu onifere kan dani, o si nrin ilẹ wo kakiri. Şamọ-şamọ Ijẹbu kan wa lori igi pẹlu ibọn şakabula. Bi Abudu Şaji ti ngun ẹşin lọ, bẹni ijẹbu na ta a nibọn nigbaiya, ni Onifere ba tẹ fere bọ ẹnu.

Eyiti a nwi yi pe, awọn ọmọ ogun ti de, Oyinbo ti o şiwaju awọn Ọlọpa nigbana paşẹ pe ki nwọn lọ gbe garawa epo Peẹrol wa, nigbati nwọn gbe de, aşe, ogun awọn Ijẹbu pọ ninu igbẹ na.

Awọn Ọlọpa bẹrẹ si fun epo na sinu igbo, awọn Ijẹbu ko kuku ri iru epo bẹ ri, nwọn şebi ojo lo nrọ, nwọn wipe Ha' eji mi rọ, Obaamita re mi ro'jı p'owọn.

Nigbati nwọn ti fun bi iwọn Garawa mewa epo Petiro sinu igbo tan, nwọn ta afọnja kan sinu rẹ, igbo gb'ina, awọn Ijẹbu to wa ninu igbo na jona rau-rau.

Bi ede "Danasungbo" ti şe bẹrẹ niyẹn, ti ara Eko fi npe awọn ara Oke ni Danasungbo, ti Ijẹbu gan ni ede na je.



Nje nwon fe gba bolu lose yi? fi egbogi ajebidan pa awon ibiti o ndun o





**Kere o!**

A ti ni orişirişi ogun Germany to şeşe de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7. Egerton Road, Lagos



**Lagos Race Club**

AUGUST MEETING 1956

SATURDAYS 21st & 28th JULY, SATURDAY 4th AND MONDAY 6th AUGUST, 1956.

Provisional Programme and Entry Forms can be obtained on application to the Secretary, P.O. Box 51, Lagos or at the Race Course

## Enia F'ori kan eran Agbo niwo Pa!

KISI. Agbo irohin wipe larin oja ilu Kisi, ni iso ibiti nwon nta Rago ati eran agbo, eran agbo funfun kan nja kita-kita nitori ki o ba le ja okun, enikan ko kuku mo ohun ti o ri ki o to ma se be. Lati owuro ni eran na ti wa ni alafia.

Bi eran na ti nja toyi, ko yo awon egbe re yoku lenu. Nigbati o se ti oja kun, eran yi ja okun, o si bere si la arin oja lo titi o lo kan omokunrin kan ti o joko to fehinti, o si kan ni wo.

Ohun ti o ya gbogbo enia lenu nibe ni wipe, nigbati eran na fe kan okunrin na niwo atari ni o fi gba iwo na.

Laifa oro gun nse lokunrin na bora sile, ti o si bo sita gbangba ti on pelu eran agbo yi wa woya ija. Ariwo ta wipe agbari okunrin na yio tuka, sugbon si iyalenu gbogbo enia, nse ni iwo eran agbo na se, o si doku. Okunrin na si tun pada si aye re lo joko.

Ngbo, enyin okawe wa, kil'eti mo iru eyi yi si o?

## Kilofa Idi Oro Nwonyi ?

Olotu,

Mo ti gbo lenu awon gbajumo enia wipe ojogbon enia ni Alagba Ogbeni J.A. Are-egbe. Inu mi yio dun gidigidi bi Ogbeni yi ba le ladi oro nwonyi ye wa, tabi ewe, bi a ba si ri ninu enyin Okawe wa ti o le se itumo oro na pelu yio dun mo wa. Awon oro na ni wonyi:

1. Kini idi re ti a fi npe gbogbo awon ti o nje Lawani ni Amubiqya (b) Ti a fi npe Alli ni Balogun (d) Ti a fi npe Buraimo ni Dende Elekun. (e) Ti a fi npe Salami ni Agbaje, (f) Ti a fi npe Abu ni Son doko (g) Ti a fi npe Yusufu ni Amudaniyu.

2. (a) Aburo wo ni Dada ni ti o si gboju ju Dada lo
(b) Ese ti nwon fi npe Idowu ni Esu lehin Ibeji?
(d) Tani won pe ni Alaba Idogbe ati Aina?
(e) Iru omo wo ni nwon npe ni Ojo Ki lofa ti awon Ijebu ko gbodo je Ojo?
(f) Iru omo wo ni a npe ni Oso?

Mo duro nihin
Emi ni,
Ayanrinde
Ara Eyeba

## JAMBA MOTO NI IPINLE IWO. ORUN

### Larin osu mefa

Ibadan- A gbo wipe enia mokandinlogoje (139) ni o ku iku jamba moto ni ipinle Iwo-orun larin osu mefa pere: iyen ni lati ojo kini osu January titi de ojo kini osu June, 1956. Igba mejidinladojo ni jamba moto sele.

Eyiti o buruju ninu jamba na ni eyiti o sele l'ona Ado-Ekiti ti emi enia metalelogun fi s'egbe, de ninu won je awon omo ilewe to wa ki Oba obinrin k'abo nilu Ibadan, ti nwon si npada lo si Ibudo won lehin ti oba ti lo tan.

Ki Oluwa sowa lowo ewu ona.

## 'Age'moje farakorin:

ONITSHA. Okunrin kan ti a npe ni Aselo, ni on pelu ara'binrin re jijo se gbolohun aso, ti o di ohun ti awon mejeji di mo ara won ni ijakadi.

Nigbati Aselo s'akiyesi wipe apa on ko ni ka ara'binrin re yi, lo ba di ehin mo ni eti, o ge e kuro tan o si tun gbe eti na mi. Nigbati oro yi de iwaju adajo; Inu bi adajo si iru iwa ti Aselo hu yi, Adajo da a lebi, o si pase wipe ki o lo si ewon odun meji pelu alo nitori ti o so ara'binrin re di alabo ara.

Iru iwa ki a ma genije bayi ki a si ma gbe mi, je eyiti o wopo ni apa ona Gabasi. Abuku ni awon nka si ki eni kan ge enikeji je tan ki o si tun gbe mi, ha! iwosi oko ero lo je loju won, ote ija na ko si ni tan nile titi ti eniti a geje na yio fi gbesan, yalo niran keji tabi eketa. Ota orun ko gbebo ni awon meje yio je si ara won


### IMORAN FUN EYIN ABIYAMO

Enyin abiyamo ewa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma nba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

OMORELA BABY MIXTURE
*(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)*
O wa Lodo i—

COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS



## Awon Dokita Fi Han Wipe
### Ose Palmolive Le jeki Ara Re Dan Ki o jolo Larin ojo Merinla



**Ara Mi Dan, O Si jolo Nitoripe**

**Mo Tele Ilana Ti Awon Dokita Se**

*1. Fi Ose Palmolive we Oju re*
[illegible]




EPO ILE AFIRKA NI A FI SE OSE YI

COLGATE PALMOLIVE LO'SE

# ELETI OFE

A-NIU-WON KO SE WI L'EKO
EDITORIAL OFFICE & WORKS    CABLES & TELEGRAMS
23, Kosoko Street, Lagos    "ELETI - OFE LAGOS"
P. O. Box 467    Phone 23379

VOL. VIII. NO. 473,    LAGOS, SATURDAY JUNE 23, 1956.


## Kosi Eyiti o san ninu omo Bankale

Eyi ti o nje e r u ni, tabi eyiti o nje erupe? gbolohun ti a fi se etin wosika wa ose yi ni o wa si okan wa nigbati a gbo ẹlaye oro ti awon alabojuto to wa ninu igbimo L.E.D.B. Wo'le wo'le se ni ipade nla ti a ṣe enia orin ilu Eko yi, ani awon ti ile wiwo na ti kan ibugbe won se ni gbangba te u ni Ita Akanni l'ojude Oloye Dokita Maja. Gegebi a ti te si apakan iwe wa yi, kini ohun ti a le se ni ninu fun eniti Ikoriko pa iya re je? a ti kesi awon igbimo L.E.D.B. wipe ki nwon se eto ki a on enil e ko ile won gegebi egbara won ba ti mo, ki a ma s'opo tun ma wa ona alumokoroyi fi se eto ile wiwo mo. A gbo wipe igbe ako gba, ako g a" l'ogb jikan ninu ipade na.

"Orisa b'o le ismi, se mi bi o ti ba mi" ni owe Yoruba wi. Bi awon alase wa ko ba le fi eso tun ilu wa se, o ye ki won jeki awa ti a je onilu se atunse ilu wa funrawa. Ewo niti ki a ba ni tunluse ni tipati a bayi? Nwon ni pepese, ilu Eko ni Olu ile Nigeria, ti enia ko tile so, tani ko mo wipe iru ilu Eko s'owon ninu ilu Nigeria, laikoiti wo'le Onile fi te opopo ona.

Ohun ti o je iyanu fun wa ni gbolohun ti nwon ni Ogbeni T.O.S. Benson so wipe ko si eniti o fi iwe ranse si igbimo wipe awon enia ko fe eto ti ile wiwo, sugbon gegebi o ti so pe on yio fi oro na siwaju awon igbimo awo'le wipe awon a r a i l u Eko ko fe ki a wo'le won, ao dawo iwe wa duro bayi lati gbo abo re.

Kosi omo ti o san ninu omo Bankale - Ejeki Onile ko ile re funrawon.

---


E Ma Ka Iwe Irohin
Eleti - Ofe
Ki E Si Ma Polowo Oja
Yin Sinu Re


---


AKIYESI PATAKI

Bi o ba fe ra Eleti-Ofe tabi o fe polowo oja sinu re,
LO SI:
18, Race Course Road,
OKE-PADI, IBADAN.

E mu irohin wa tabi ohun to ba je edun ckan yin, ki e si ma ka Iwe ELETI—Ofe nigba gbogbo.


## Orin Sobo l'ojo ti oyin le awon egbe Onisowo kuro nibi ase Alake.

(Lati owo N. B. S. Lagos).

Mo ti re mo tun sebin de, Emi eni igba kan.
Ojo ko l'ojo, ojo ko l'ojo;
Ojo ko l'ojo egbe Onisowo wa je raisi l'Ake 'm'eji;
Ijoren ko dun. Dede onife'lona re oyin nle kiri
l'Iworiwo! Li'o otan yi, oyin fefe ta Jinadu pa,
Li'ona Ijaiye: oyin je won de sokori
Lat'enu odi Ijaiye,
Igb'awon olowo nla eyi a fori re sounje nalo tan
Awon awooopayi re wo Kotu lo fi onje je.
Obasami - oli bata ijoren ko duro de olomeje re!
Sunmonu Oko se wunren kan lijoren erin pani;
Agbalagba, o nlo s'oko, o gba Kemta Ejigbo:
Bojaseko'yi a orogun ja, iru yen iba doju ti ni!
Sunmonu, o ko duro m'asibori, o ngesin?
O ma dun'nia poju!
Ikereku'yi wa lijoren je'egbagbeje
Nwon ko kan duro s'akin:
Akilawon'yi s'oroju inu won gesin gb'gbein!
Ko kan ya sile Abowaba mumi:
Boj'aseko'yi ogun wa ng-hun!
Iru iyen iba doju ti ni!
Akilawon, o nti Ake lo s'Ikereku
O ba t'Ago Odo lo i? O ma bogiri o!
Awa ara Ake ko kan sare kiri,
Awa m'eso poju.
Awa omo ana re Sekiteri pe
Ki a lo gb'awo onje won li Kotu!
Boj'aseko yi a tun ar'ogun, ja, Ake ogun o;
Ng ko sawoda.
Orin:- "Biri - biri oyin ma nta
Ko je y'ogan
Biri - biri oyin ma nta
Ko je y'ogan t'omo re"

---


Mo Gbadun Siga
Pirate




PIRATE

Ni Siga To Dara

## FUN IRANTI OHUN TO SELE NI 1927

EKO. Awọn Yoruba lo npa owe bayi wipe, bi ọmọde ba ṣubu, yio wo iwaju ṣugbọn bi agbalagba ba ṣubu, yio bojuwo ẹhin. Ẹjẹki a ṣe iranti diẹ ninu awọn ohun ti o ṣẹlẹ ni ọdun 1927.

Ofin owo ori bẹrẹ lọjọ kini oṣu April 1927 awọn Jọnma Musulumi, Jọnma Alalukurani Jọnma Ahmadiya, ati Jọnma Mọṣalasi Ọlọkọ lọ ba Aṣoju nipa ọrọ owo ori na Major Birrel Grey sọ fun wọn pe, ọrọ yi ti di ofin, a si ti tẹ jade ninu iwe irohin Ijọba. Yesufu Omidiji Akọtun jẹ oye Ọlọtọ lẹhin Oloye Akinlolu Akodu Ọlọtọ lọjọ 17th oṣu Feb 1927. Akilotu si lo pe e lẹjọ wipe ni tori ti o fi agbara fọ ilekun wọ iga, ki Adajọ ba on gba adọta-le-ledẹgbẹta poun lọwọ Omidiji. Osi gba Lọya Zizer. Dokita Manuwa, ati Dọkita Doherty lo jijọ ba ọkọ oju omi ti a npe ni S.S. Wadai de lati ilu Oyinbo nigba kanna lọjọ 20th March 1927.

Ijọba mu awọn Ọgbẹni J.K. Coker ati A.K. Ajiṣafẹ wipe nwọn sọrọ odi si Ọba Alaiyeluwa Alake Abẹokuta, Ọgbẹni Isaac Thomas di olotu iwe irohin Akede Eko, lọjọ 15th oṣu July 1927. Oloye Onitana pe awọn ara Idunmọta lẹjọ pe on lo ni ilẹ Idunmọta, on si ni ki ijọba san owo ilẹ na fun lọjọ 15th oṣu Dec 1927.

## Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe

**Now Available**
BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS, DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just Write, Call Or
Phone 21372
**IKORODU TRADING COMPANY**
20/28 BALOGUN STREET
(P. O. BOX 395) LAGOS.
AND
NEW COURT ROAD,
IBADAN

## Ibere Lodo Lemomu Ajakuta

Olotu,

Jọwọ gba mi laye lati ṣe ibere ọrọ nwọnyi lọdọ Alufa Lemọmu Ajakuta.

1. Iru awọn enia wo ni Lemọmu npe ni Onigbagbọ?
2. Tani sọ fun u pe Adura on ko gba?
3. Iwe wo lo fihan pe, Ọlọrun ko ngbọ adura Onigbagbọ?
4. Kini iyatọ larin Ju ati Onigbagbọ?
5. O ha nṣe awọn Ju nwọnyi ni Ọlọrun kọ adura wọn ndan?
6. Kini Lemọmu ṣe mọ pe Onigbagbọ ko tin ọna ti Ọlọrun fẹ.

Njẹ bi Lemọmu ko ba le dahun awọn ibere nwọnyi awọn Imale yio mọ daju pe, Ọgbẹni na koyẹ li ẹniti o le joye Lemọmu.

Awọn Keferi Abọgibọpẹ mbẹ nibẹ. alufa yi ko sọ pe ki nwọn wa gba ẹsin Imale, ayafi awa ti a kọ eṣu ati gbogbo iṣẹ rẹ silẹ ni Lemọmu nwasu fun lati wa gba ẹsin Imale. Nitorina mo fẹ ki Alufa Lemọmu Ajakuta la a ye mi

T. Olu Fred

## The National Bank Of Nigeria Limited

### ILEYA SHILLING FUND - JUNE 1956.

Depositors in the Ileya Shilling Fund are hereby reminded that, in accordance with the regulations governing the Fund, they may withdraw their deposits as from Monday 25th June, 1956.

Withdrawals can only be made by depositors in person and on production of his passbook. In case of distant depositors, early application for a withdrawal form should be made to the Manager of the Branch concerned, such application to be acompanied by the depositors passbook, for interest to be entered up.

Withdrawals for the year will close on the 21st July, 1956 and depositors who fail to withdraw on that day cannot do so until next Ileya.

Payment shall be made in the following alphabetical order of the Depositors' surnames on the date shown hereunder and contributors who fail to apply on the prescribed date shall not be attended to untill Monday, 2nd July, 1956.

| | | | | |
|---|---|---|---|---|
| A. | to | B | Monday | 25th |
| C. | ,, | H | Tuesday | 26th |
| I. | ,, | N | Wednesday | 27th |
| O. | ,, | R | Thursday | 28th |
| S. | ,, | Z | Friday | 29th |
| A. | & | O | Saturday | 30th |

For the year 1957, deposits will be taken as from Monday 23rd July, 1956.

BY ORDER OF THE GENERAL MANAGER

**AWON OJOGBON ONISEGUN EHIN FI YE WA WIPE**

BI A BA NFI EGBOGI







COLGATE DENTAL CREAM FO EHIN

KO NI JEKI EHIN ENIA BAJE, O D.. RA PUPO



Iṣẹ ti Egbogi yi nṣe ni wipe, eyiti o nho bi ọṣẹ yẹn, yio wọ gbogbo pala-pala ehin, yio si yọ gbogbo ajẹsi kuro, ko ni jẹki ẹnu run, ko si ni jẹki ehin bajẹ.




O njeki ehin funfun, enu ko si ni run mo.

## joyo Isegun Miringindin Le Gongo

Ojo kojo ti awon egbe Afenifere se ayajo isegun won lori egbe Alakuko nilu Eko, ojo na fere l'adun ju ojo ti Oba o nilu Eko lo, iba ni wipe, ki a ta asia fun Eko.

Nitori awon oro ti Awolowo se lojo Jimo na ni wipe, Yoruba lo ni ilu Eko, Yoruba lo si tedo, bawo ni ilu na ti se wa di ilu bi o da ki o wa? Nigbati Ado ajoba nibo ni awon Ibo wa, Nigba aiye Oba Akisemoyin, Idewa-Ojulari, Adele Kini, Oluwole, Akitoye Dosunmo ati Oyekan nibo ni won Kegbede wa.

Awolowo so wipe on ati awon egbe re yoku yio ja ijakadi lati da ilu Eko pada si arin ile Yoruba yoku.

A ba le se ore tan, ki a ni kiu wa gba idi pgola bi? Mo gebi ore ni Eko se ti o gba won ni alejo. Nigbati nwon si koko de ise Boyi-boyi ni awon nse, awon alaimore jebe, nwon mube won wa fe ba ibe je. B'o ba kanran ti Kiniun yio fi se akapo Ekun Olode ni yio fi owe mu ode tire.

# Fun Alafia Ara ati Agbara Ninu Eje



HOMMEL'S

# HÆMATOGEN

Lo sodo awon ti o nta egbogi Hommel's Haematogen l'oni, ki o si ra igo kan. Ki o ma lo nigba-gbogbo titi ti yio fi bere si fun o ni agbara, nigbati yio ba fi to ose kan, awon ore re yio rii, ati pe iwo papa yio ri ayipada iyanu ninu alafia ara to ajade ni oju re.

FUN OMO TO ŞE AISAN TI O SI NRU



pe ki egbogi yi je awon o L

*O wa ninu Igo fun tita ni Sobu egbogi kakiri Ile Nigeria. Bere lodo Asoju wa:-*

ALBAN PHARMACY LIMITED
2, Victoria Street, P. O. Box 461.
LAGOS — NIGERIA.

# Egbe Afenifere ati Egbe Alakuko

Ni ojo kan bayi ti oju orun dara, ti awon eiye si bere si korin, afefe nfe, orun si nran, ni awon egbe Afenifere fiwe s'ode wipe awon fe dibo. Okan ninu awon egbe Alakuko gbo o si lo ba okan ninu omo egbe Afenifere, eyi ni oro ti awon ba ara won so:

Akuko — Keke - re ke - e! onile mo kago o.

Afeni: — Ago ya o, iwo ta nuni?

Akuko — Emi ni Akuko galaja idi Ege ti ko njek'eni gun igi Ege,

Afeni, — Ha! Bi iwo ko ba jek'eni gun Ege, epo Ege ni yio pa o

Akuko — Tile pa eyiniti na. Mo gbo pe, e nfe dibo yes or no?

Afeni: — Bi mo ba fe dibo kini ohun ti o kan o lati se Soboleson, Sobosola nipa re, kini a ti se pin itan Aja ki o to wa kan Lemomu.

Akuko — Yoruba land is no man's land, iru wa, ogiri wa ni, tabi awa pelu nyin ko lo jijo te ile Yoruba?

Afeni: — O dara, koburu, bi awa lo ju nyin lo, bi enyin lo ju wa lo, ipade di ibadan.

Akuko — Aiya wa ko ja, beni ko si mu wa lomi, pelu agbara tipa-tipa, niwon igbati Adelabu Penkelemesi ba si mbe ni Ibadan aiya ko fo wa.

Afeni: — Iwo ko gbo orin ti iru awon egbe nyin nko lasiko kan nigba aiye Bale Akintayo awon Olosa Ibadan nkorin bayi pe, "Akiwande ja ranin-ranin, awa lao ba ile yi je" Eyi ni esi ti nwon si fun won lati owo Balogun Ibadan pe "Nibadan yi, ao foju ole ri nkan ni Ibadan yi"

Akuko — Ona wo le o gbegba, nitori a poju nyin lo.

Afeni: — Gidigbo, gidigbo! Heya! Bi e ba ngbo gbi A. G. lo da o.

## Anfani Eko Ofe

Nigbati Ijoba Iwo-orun bere eto eko ofe ni idunrin, odegbata enia le awon to fe je anfani ti a pese fun igba enia.

Loni yi, awon bi egba enia lo ti je anfani na lati ko eko lofe ni ile-iwe giga ati ni ile-ikose.

Ijoba fun awon Ekun to rehin ninu eko ni owo lati mojuto ilosiwaju eko-giga l'agbegbe won.

Igbimo ti nmojuto Idagbasoke Ohun Ogbin ni Ipinle yi ti fun otalelugba-o-le-kan enia ni anfani eko-ofe lati jeki orisirise ise-owo ni ilosiwaju ni Ipinle ye



Ile-ise Alaroye Ijoba Ipinle Iwo-orun lo se ikede yi.

## Irora Ibadi

Egbogi ti a se fun niyi:-

Nigbati ibaradi ba ndun ni, oluwarẹ nfẹ itọju bi a ko ba tete fi egbogi rẹ ko loju, aisan yi a ma fa Ẹhin-didun. Lakuregbe, Wodi-wodi, Akọ Ẹsanri ati Igunfẹ-buruku wa.



Obun ti o nfa nigbati Kidinrin ko ba sise lara, sugbon bi enia ba ti lo egbogi yi alafia yio desi oluwa re, nitoripe ara Kidinrin ni yio ti sise. Dasewo lo ra ni sobu egbogi.

**DE WITT'S PILLS**
for Kidney and Bladder Troubles

## Odun Egungun Nilu Ibadan

Ọdun Egungun yio bẹrẹ nilu Ibadan ni ọjọ Ọsẹ (Sunday) ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun oṣu June yi.

Ẹ KO GBỌDỌ NA ENIA

Alaiyeluwa Ọba Olubadan ti sọ wipe ẹnikẹni ko gbọdọ lo ẹgba atori tabi ki o mu ọpa dani tabi ohunkohun to le ṣe enia leṣe, tabi ohun ija ni ẹnikẹni ko gbọdọ mu dani tẹle Egungun lẹhin.

Awọn Ọlọpa oba yio ma yi odo kakiri, ẹnikẹni ti nwọn ba ri mu ti ko tẹle aṣẹ yi, yio f'arakorin.

Ogun agbọtẹlẹ ko np'arọ o.

## PALM LINE MANAGING DIRECTOR DIES

The death is announced of Mr. T. B. Bragg, the former Managing Director of Palm Line Limited. He could boast of serving the Company for fifty-two years, when he retired in 1952.

Mr. Bragg joined the Niger Company in March 1900 in the Shipping Department at Liverpool.

In 1929 he was made Manager of Shipping Department United Africa Company Limited, when the Niger Company merged with African & Eastern Trade Corporation to form the Company. On the formation of Palm Line Limited in 1949 he was appointed Managing Director of that Company.

Mr. Bragg was 69 years of age The funeral took place on Tuesday 5th June.

## Rerin Die

1. Eniti a wipe, ko fi epo Olokowo jẹ Koko tutu (nwon fi ṣe egbogi fun ni) O dabun wipe bawo ni enia tiṣe ni lati fi epo olokowo (20 Cowries) jẹ koko kekere yi Hẹwu! epo olokan niyo.

Nigbati o jẹ koko tan gbogbo ona ọfun bẹrẹ si yun nini o wa ko ekanna ti ọna fun rẹ sugbọn ko denu nwọn ni ki o f'a epo o mu epo igo meji. Ẹ ba mi rẹrin Ha-ha-ha-ha.

2. Obinrin kan ti o ṣe si Oriṣa, ti Oriṣa si bẹrẹ si baja, awọn enia dide lọ be Oriṣa na, Oriṣa si gba. O ni ki nwọn sọ fun obinrin na ki o ṣe To! Nitori ti irora ati wahala ti mbẹ fun obinrin na, o wipe, ẹ fi mi silẹ o jare! ako bọọ le ma ṣe To-To-To- Ẹ ba mi rẹrin. Ho-ho-ho-ho.

3. Obinrin kan nle Akukọ adiẹ rẹ lati mu obinrin miran ti o sakiyesi pe nwọn fẹ mu adiẹ na fe lati ba wọn mu adiẹ yi, lojiji ni ese rẹ yọ o ṣubu, o si fi ejugun bo Iya aladie si wipe Hẹ! pele o, obinrin keji si dahun pe O-o-o, a ki ma dupe ara ẹni. Aladiẹ wipe dupẹ bi ti ewo! Iwọ lo ba ni adiẹ na ndan? Ẹrin Hi-hi-hi-hi.

## OLA NGORI OLA



OLOYE DOKITA MAJA

Aworan inu iwe wa yi niti Oloye Dokita Akinọla Maja (Baba Eko) ẹn ni Ọlọla Gomina ilu Ibadan, ni ipinlẹ Iwọorun yan sinu igbimọ ilọsiwaju Ikeja ati agbegbe re.

Awọn enia ti yio wa ninu Igbimọ na ni Alaga Igbimọ Ikeja, aṣoju lati igbimọ Muṣin, Agege, Aṣoju Oyinbo Reluwe, ti Oyinbo Ọlọkọ Ofurufu, Alabojuto iṣẹ owo ati aṣoju awọn to ranṣẹ ọja lati ilu Oyinbo.

Oloye Baba Eko Pegede.

No. 73/S.2/VOL. VII/191

## Western Nigeria Information Services, Western Region, Ibadan.

VACANCIES FOR ASSISTANT COMMERCIAL ARTISTS,

Applications are invited by the Director, Western Nigeria Information Services, Ibadan from suitably qualified candidates for appointment as Assistant Commercial Artists in the establishment of the Department of Information Services, Wester Region.

Salary Scale - E.3. - £288 x 12 - 300;
£315 x 15 - 375.

For full particulars see Western Region Official Gazette No. 33 of 14/6/56, Notice No. 449.

Closing date 1st July, 1956.



## Awon Apania Ku Ilu Oro



ISRAEL NJEMANZE

Idajo kou se lori awon ti o gbe lu Tor Iku akerin Olobo..., Israel Njemanze ti nwon so pa ti nwon si ko da si oju irin oko Relwe ni Surulere ni ojo kejo osu April, 1955.

Awon enia merin ti idajo se le lori na ni Samuel Jegede, Cyril Anikwe, Peter Nwongu ati Michael Adeyemo ti a to awonran won sinu iwe wa yi. Nwon ku ikun iyegi molese pa ni ojo kokandinlogun osu June 1956.



Machael Adeyemo





Peter Nwangwu



Samuel Jegede

## Ajodun Kesan Eleti-ofe

BI OLUWA BA WA PELU MI, TANI LE KOJU IJA SIMI

Adupe lowo Olorun fun idasi emi wa ati ibukun Re lori iwe Irohin wa Eleti-ofe, ti o dagba di omo odun mesan l'ose yi. Ope ailopin ni ase fun Oluwa, Oba Oga-Ogo, ti ko je ki a ni ipalara ti a fi la odun mesan koja.

A dupe lopolopo fun enyin alatilehin wa, nipa ipolowo oja sinu iwe Irohin wa (Advertisers) enyin Asoju wa nilu Oke, nile Hausa (North) ati ni Oke-okun (Gold Coast) to fi kan awon Asoju wa nilu Oyinbo (Europe). Onibara wa, Okawe wa ati Olota iwe Irohin wa, (Vendors) gbogbo nyin ni a dupe fun gidigidi.

K... alafia ati ibukun sil... ti Olodumare n... a wa gbe lai ... titi lailai - A se ope o.





## Ogun Aran (Ejo Inu)

Aradan Worm Expeller je ogun aran pataki fun omode ati agba okunrin ati obinrin. Re igo kan lati va gbogbo awon aran buburu ti o nba o ja ninu danu. Bi o ti npa aran, beni o npa eyin won. Wa ra tire ki o to tan. Igo kan je 2/6d. Owo-Okó si je 1/-.

THE EGBA TRADING ARADAN STORES,
18, Denton Bridge Street,
P.O. Box 2, Ebute Metta.




Ogbeni Adegoke Adelabu

Ni ojo Monday ose yi ti i se ojo kejidinlogun osu June, 1956, ni adajo Kotu Gangan (Assize Court) nilu Ibadan da Adelabu sile ati Alli Oyebanji ninu esun agbowo ibole ati oluranlowo nipa ese na.

Niba soki Adajo so wipe on ko ni itelorun si eri ti awon eleri ijoba merérin je, nitoripe eri won ko dogba, atipe bi a ba ni ki a gba eri won, awon eleri wa ni owo nlan ese na, nitoribe, on ko le gba eri won.

Adajo tun te siwaju ninu idajo re wipe alaye ti Adelabu papa se lori a nlo ta awon to nwa'se soro lori oro... ko te on l'orun sugbon eyini ko se iranlowo fun ejo ti ijoba nba Adelabu se.

## Mohamed Ni Olutunu

Olotu,

Gba mi laye lati dahun ibere Ogbeni Olakunle ara Ogbomoso to so wipe Jesu ni Bibeli npe ni Olutunu, nitoripe Emi mimo yi na ni Jesu. Mo ni igboiya lati fi han Olakunle wipe, ki a to bi Jesu, ni Emi mimo ti wa, ti o si ti nsise pelu awon enia. Gbogbo awon Woli ti o so asotele lati igba aiye Noa ati ki a to bi Noa papaa, li emi mimo ba sise.

Ranti po nigbati Olorun le Adam ati Efa jade kuro ninu ogba Alijanna, Olorun lo ran Emi mimo si Ichinna, tobe ti o fi bere si fi ede fo, eyi ti o si jeki o ri oju rere Olorun. Iru ede ti o fo lojo na mbe ni ipamo lowo wa. Bi enia ba si nlo ede na nigba gbogbo, Olorun y'o forijii.

Mo tun gba Ogbeni Olakunbi niyanju, ki o lo wo Bibeli re. Deut 18, 19. Iwe Johanu 1. 19-21 ati ori 16. 12-13, Korinti ori 13. 9-10. Peter 1. 21. Gbogbo oro ti nwon so nibe, Anobi Mohamed ni nwon nso nipa re.


## Enjoy Your Own —Songs—



Songs By Your Own People in the way you love masterly rendering of additional AFRICAN MUSIC is yours, on obtainable from

**The Association Of Nigeria Gramophone Dealers....**

THROUGHOUT NIGERIA


Printed & published by The Union printing and Publishing Company, 25 ... Street P.O. Box 467 Lagos Phone 23378